IJOBA AGANYIN LE OMO ILE NIGERIA WALE



SEE YOU PAY THE
CORRECT PRICE.

ELETI OFE
A-NJU-WON KO SE WI L'EJO

U. T. C.
SERVES
YOU
WELL

VOL. IX No. 531. ELETI - OFE LAGOS, SATURDAY, AUGUST 3. 1957. KOBO MEJI (2)

# Ijoba Aganyin le omo ile Nigeria wale



Aworan ti a nwo yi ni awon Prime Ministers ti o wa ndou awon ilę to nso ede Gęsi ti a si ti so di ominira. Ni arin meji aworan yi ni oba obinrin ilu Gęsi ti a npe ni Elizabeth Keji duro lowo otun oba obinrin na ni Prime Minister ilę Gęsi, lowo osi ni Ogbeni Nehru Prime Minister ilę India, eniti o wa ni egbe Nehru ni Dr. Nkruma ti o nse Prime Minister ilę Ghana.

Ijoba-ilę Ghana na l'o se ofin ti nwon fi le awon enia meji kuro nilę Aganyin, Ghana, ati Olotu, Iwe Irohin kan ti o je ara ilu Saro. Oro yi ti bi Ige o ti bi adubi si ilę Aganyin ni isisiyi.


A GIFT FROM HEAVEN!
BAMWO BABY MIXTURE
OF EXCEPTIONAL VALUE IN PREVENTING SICKNESS, CURING FEVERS, COUGHS, MEASLES AND TEETHING AILMENTS. ENSURES SOUND SLEEP.
PRICE 2/6 POSTAGE 1/
THE EGBA TRADING ARADAN STORES, 41 DENTON STREET, P.O. BOX 2, EBUTE METTA & BRANCHES

# Owo Olopa te Egbe Olosa

Awọn enia mejọ ni ọwọ ọlọpa tẹ fun ẹsun ole ti nwọn ko wa siwaju adajọ ni Kotu yaba ri ọsẹ to-kọja.

Awọn ni Amusa Akinbi Ganiyu Sadiku, George Arẹgbẹ, Oyetami Ajani, Bandele Ogunleye, Sikiru Musa; Ayọ Ṣotade ati David Arẹgbẹ.

Nwọn fi wọn sun ẹsun wipe awọn ọdaran na wọ ile Ọgbeni Ojẹlade ni No 2 Ojẹlade Street, Mushin ni dede agogo mẹta oru, pẹlu ake ati ada, ati pe okan ninu wọn tilẹ pa Ọgbeni Ojẹlade lara nigbati ko fẹ jẹ ki nwọn ko ẹru on. Ẹru ti nwọn ko lo le ni irinwo poun.

Nwọn fi ẹjọ wọn si ọjọ kẹfa oṣu August 1957.




Kere o!

A ti ni oriṣiriṣi ogun German to ṣẹṣẹ de, fun oniruru aisan tokun ti tobinrin. Yete wa ra tirẹ k'o to tan.

J. A. AJAO BROTHERS

MEDICINE STORES

7, Egerton Road, Lagos.

## AKIYESI PATAKI

**Enikeni ti o ba fe ra Iwe Irohin Eleti - Ofe Ki o lo si Idi Moto, Ogunpa, Tabi Lodo Asoju Wa, Ni 107, Oke Padi, l'egbe Sesi Aguda Nilu Ibadan.**



Awon gbajumo enia gba wipe...



Eyi ni lati jẹ ọti Onirawọ (Star Beer) o ṣoro ki enia to le ri iru ọti bẹ mọ! Awọ rẹ ti o dara loju, ati gẹgẹbi o ti nta winni-winni jẹ ami wipe ọti ti o dara ni Ọti onirawọ!
Agb'ọti! mu ọti Star Beer mẹta si wa.

STAR



Oti Star Beer je eyiti o dara ju

beni Sammy Sparkle wi



Ọti ti o ba dara nilati ni awọn ohun elo pupọ ninu, o nfẹ ọgbọn ori, oka Barley ti o dara ni a fi ṣe. Awọn ogbogi apọn'ti lo ṣe ọti Star Beer on ni a si gba wipe ko si ọti Bia kan ti o le farawe ni Afihan gbogbo ọti bia agbaiye ni ọdun 1954. Ọti ti o pe iye nişe



# Awon obinrin ile Nigeria nilu Oyinbo

Awọn obinrin ti a awo ninu aworan yi ni awọn ti o nṣe iṣẹ itọju awọn ọmọ kekeke ni ilẹ Hausa, awọn oyinbo ti o si wa larin wọn ni Mayor ilu Exeter ati iyawo rẹ, orukọ rẹ njẹ Ọgagun Lt Col R. H. Creasy.

Oyinbo kan ti o tun wa pẹlu wọn ni Sheriff. Ni apa osi, ni ipo kẹrin, ọkunrin Hausa ti o duro larin wọn ni Alhadji Isa Kaita, ọkan ninu awọn Minister ilẹ Hausa.

Nilu Exeter ni awọn obinrin na fi ṣe ibujoko, a si fun wọn ni ọsẹ meji lati fi ṣe ayẹwo yika ilu Devon, awọn si foju si gẹgẹbi awọn ti nṣe akoso ilu ati gẹgẹbi awọn obinrin wọn ti nṣiṣẹ si, fun ilọsiwaju ilu.

Nwọn de ibiti a gbe nṣe itọju egungun ti o bajẹ, tabi ti o yẹ lorikẹ ara; nwọn de ile igbẹbi tabi ile alabiyamọ, nwọn si de ibiti a gbe nkọ iṣẹ agbẹ, awọn obinrin na ko ni pẹ pada silẹ Hausa.






# Ajao ko du oye Balogun



Agbọ wipe Oloye Otun Ọyọ, J. A. Ajao ti ilu Eko du oye Balogun ilu Ọyọ ni asiko kan. Eyiti Alaiyeluwa Alafin Ọyọ fi da Ogbeni Abiọdun Akerele l'ola ni ọjọ Tuesday ọsẹ tokọja. Oloye Ajao na sọ wipe irọ ni ẹniti o sọ wipe on du oye Balogun nilu Ọyọ da mọ on, on ko du oye rara, ẹniti o pa wu "Iku baba yeye" Alafin Ọyọ, l'o le fi oye ilu Ọyọ da l'ọla.

# Awon Egbe W.H.O. Gbogun Ti Ogodo

OGOJA Awon egbe kan ti a npe ni World Health Organesation ti fi lo wipe, arun ete, arun Ogodo ati arun masun-masun poju nile Nigeria ati wipe awon ti setan lati gbogun ti awon arun na.

Laipe yi awon agbajo egbe Onisegun oyinbo bere ise won ni agbegbe ile Ogoja, a si gbo pe oke meta enia (60,000) ni nwon yewo ti nwon si se itoju won.

Awon arun pataki ti o wopo nilu yi ni arun ete, arun Ogodo ati arun masun-masun. Opolopo enia ni arun yi ti pa danu.

## AWORE

Oloriṣa oko, ko mbiad ẹfun, abiyamọ ko nkọ gele osun, ... [illegible] gbarẹre wa jẹka, ... [illegible] rẹrẹ. Owo gbarẹ ... [illegible] ẹrukuku gbarẹrẹ ... [illegible] eiye gbarere.

# ELETI QFE

A-NJU-WQN KO SE WI L'EJO

EDITORIAL OFFICE & WORKS CABLES & TELEGRAM

28, Kosoko Street, Lagos "ELETI - OFE LAGOS"

P. O. Box 467 Phone 23370

VOL. IX. NO. 531. LAGOS, SATURDAY AUG. 3. 1957


## ANFE ASQJU

A nfę Asoju fun Iwe Irohin wa Eleti-Qfę lati fi kun awon Asoju wa ni awon ilu ti a daruko ni isalę wonyi:–

Abeokuta, Ijebu-Ode, Ijębu-Igbo, Ile-Ifę, Oshogbo, ati Port Harcourt.

E kowe si Oloto Iwe Irohin Eleti-Ofę, 28, Kosoko St. Lagos.

## Igbimo ibile Eko (L.T.C.) Ndabira

Lapakan iwe irohin wa ose yi ni a tę ikede kan ti awon Igbimo ibilę ilu Eko, (Lagos Town Council) fi s'ode fun akiyesi gbogbo enia, nipa işę awon Onişę - alę, lati owo awon Alagbaşę (Contractors).

Awon Igbimo so wipe gegebi afisun ti po lori awon Onişę - alę na nipa aiko şe işę won na deedee, işe ti o je wipe ni ojojumo ni awon nilati ma gbe, ti won ko si ni gbe fun ojo meji tabi meta, awon ko tile ngbe ti ibomiran fun bi ose kan tabi ju bęlo. Eyi ni awon Igbimo ro wipe ko le mu alafia wa fun awon ara ilu.

Awon Igbimo se iwadi ohun ti o nfa sababi yi, awon wa ri pe awon Onişę-alę miran ti ko nşe ti Igbimo Town Council ti o nşişę nilu Eko l'ofa iru iwa aişişę deedee awon Onişę - alę ti Town Council wa; nitoripe awon oşişę ti Igbimo Town Council ti o mba awon Alagbaşe şişę ma ngba ęya - miran, iyęn nipe, awon a pa işę ti won ti, awon a si ma fi asiko işę won şe işę miran l'asiri.

Lati le mu iwa aiko şişę na daradara yi kuro awon Igbimo Town Council fę şe atunşe eto işę na, şugbon ohun ti awon fę ki o ye gbogbo enia ni wipe tęlętęlę Sile meje-abo (7/6) ni Igbimo ngba fun Pokiti kokan l'oşoşu, owo ti Igbimo nna lori Pokiti kokan loşoşu je Sile mokanle-logun ati kobo marun (21/5). Nipa bę, owo ti Igbimo Town Council nfi kun owo na je Sile merinla (14/).

Nitorina, Igbimo yio nilati fi kun owo Pokiti kan loşu ti yio fi je Sile metadinlogun-abo (17/6) lati ibęrę oşu October 1957. Eyi yio je idękun fun Igbimo ti işę na yio fi le ma lo deedee. Iye Pokiti ti Igbimo ti nko tęlę je ogojile-lęgbętala din ogorun (2,540 Pails). Iye ti ao si bere si ko nisisiyi yio je edegbeta - le, legbajo (16500 Pails), nilu Eko, Ikoyi ati Ebute Metta.

A fi eyi şe alaye fun enyin okawe wa ti ko ni anfani lati ka ede Oyinbo, a si ni ireti wipe gbogbo wa ni yio gbaruku ti Igbimo ibile ilu Eko (Lagos Town Council) fun işe rere ti awon fe da'wole yi ki o le yori si rere.


Plushes, Velvets, Velveteen, Damasks & Building Materials

PLEASE CONSULT :

**Okunowo Brothers**

63 Massey Street, (Faji Market)

LAGOS, NIGERIA.

The house where Courtesy & Satisfaction are Guaranteed


## Lagos Town Council
### Nightsoil Conservancy Service

1. For some time now there have been widespread complaints about the Council's Nightsoil Conservancy Service, which is being done by contract as far back as 1954. Pails in the premises serviced by the Council are supposed to be cleared every night. The Council's Contractors, however, fail to clear these pails every night. In fact there are premises where the pails are not cleared for many days together. This is a great inconvenience to the occupiers of such premises and a danger to public health.

2. Side by side with the Council's service exists a large practice in conservancy by a number of private bodies and individuals of varying efficiency. Investigation has revealed that the men employed by the Council's Contractors indulge in private practice to an extent that has seriously undermined the efficiency of the Council's service and has been the cause of several people leaving that service to go to these unauthorised private Nightsoilmen.

3. Under the Lagos Local Government Law of 1953, the Lagos Town Council is responsible for the clearing and disposal of nightsoil from all premises in the Municipality that have no septic tank installation. Council has therefore approved the introduction by October 1st 1957, of a new scheme by which all premises in the Town shall be serviced by the Council's Countractors. To start with, the scheme will be limited to all premises in Lagos Island and Ikoyi as well as to those premises already being serviced on the Mainland by the Council. It is proposed that the service will be extended to the remaining premises in the Municipality at no distant date,

4. The new scheme will be much bigger than the one Council now operates. But a survey of all premises in the Municipality has been made by the Town Engineer and details of the extra staff, transport, and cost to cope with the expanded service have been carefully worked out.

5. The existing scheme covers approxmately 2, 540 pails and costs Council 21/5d per pail per month of daily service, while the Council has hitherto charged only 7/6d per pail. This means that the service has hitherto been subsidised from the rates to the tune of approximately 14/- per pail. The new scheme to cover the whole Munisipality will involve the servicing of about 16,500 pails. Council will charge 17/6d per pail per month of daily service. This is the amount below which Council cannot go without having to raise the rates.

6. The Council in assuming the responsibility that is already its by law hopes that the public will place public health and efficiency of the service above sentiments and give it the understanding and co-operation it needs to make the new scheme a success.

**D.M.O, Akinbiyi**
TOWN CLERK.

E Ma Ka Iwe Irohin Eleti-Ofe Ki E Si Ma Polowo Oja Yin Sinu Re

# Asape fun were jo, ti on ti were egbera

Lojo kan, Okunrin kan, ri ka ninu iwe irohin kan nibiti okunrin kan gbe ba oruko re je piti-piti. Okunrin ti nwon ba loruko je yi wa di 'e lo sodo okunrin kan ti o ti gba oye Dokita fun oro siso o wa bere bayi :-

Dokita, lodo re ni mo wa fun imoran kan ki o ko mi bi o ti to ki nse. Okunrin kan lo ba oruko mi je sinu iwe irohin kan, ewo lo to ki nse, ki nso fun wipe ki o tuba kiakia pe on ko wibe mo ni, tabi ki npe e lejo, ki ngba owo lowo re fun oruko mi ti o baje ?.

Eloye Dokita na dahun pe, ma se ohun kan. Idi re ti mo se wibe ni wipe, ogunlogo ninu awon ti o ka iwe irohin na, ko se akiyesi oro na, oju won foda. Opo awon elomiran lo kan nka iwe irohin lasan, ti ko le se itumo ohun ti o ka. Beni ogidinleje awon to mo ka, ti o si gbo agboye re ko gba gbo. Bakanna ni opo enia ti o gbowe tara, ti o si mo o ka je awon enia ti ko ni lara ti nwon ko si je ohun kan nile. Okunrin na si so pe, o dara, on gba.

# Iya ni wura, baba ni Jigin

Owe Yoruba so wipe, Iya ni wura baba ni jigin. Enia bi iya ko si, tani le se gegebi baba eni fun ni.

Iya eni ko nse egbe ogoran Misisi ti o nko awon omo ni eko ninu ilewe. Iya ti o bi George Washington nile Amerika, omo marun lo fi sile nile aiye ki o to gba orun lo, ni asiko na, omo odun mokanla ni George wa.

Iya yi je eyiti o muna ti ko je gba igbakugba fun awon omo re, ko gba won laye lati ko egbekegbe, tabi lati ma sere kakiri ojnle, owo ti o fi ma awon omo re. nwonyi lo sin won de aye ola ati ola nile Amerika loni.

Nile wa nihin, a ko le se aini iru awon obinrin gegebi ti iya George Washington, tabi awon obinrin ti o ye ki a fun ni oye "Dame" tabi oye "C.M.G.".

Bi a ba so wipe obinrin ko to awon omokunrin, asipa owe ni eyi je-Pupo ninu awon obinrin ile wa lo ti sin omo re de aye ibiti eru ko ni ba won mo, ki nwon to ku.

# Awon Olopa Ibadan Fe Ba Egun S'ejo

IBADAN— Gbangba di ekun kedere wa nyewo ni oro awon egungun meji ti o sa ara won logbe nigbangba laipe yi ni Ibadan. Ikan ninu awon egungun na ti oruko re nje Anigilaje gba ogbe to be se ti won ni lati se igbale kekere fun lodo Dokita ni Adeoyo fun ijo meje gbako- o si ti wole nisisiyi.

A gbo wipe egungun ti on tie joja so fun awon olopa wipe ideaa orun ni on ngbe, bi won ba nwa on lati ro tenu on. Egungun keji na ti o nje Iporiku ti wole sugbon awon Olopa Ibadan ti ye iwe ejo won wo, won ni lati f'oju kan adajo.

Bi awon atokun won ni won afun niwe ipejo ni, bi awon egungun na ni, ni idena orun, iyen loku ti a nduro de.

## Bi a ti se nki Ifa

Moji, mo ki Asunla; Atola; Asunrun-rere, ina ku, ku, ku lahere, enia ku; ku ku l'aba; Oluwa mi ogbojo ti awo yo; ogbojo.

No. 105

# The Nigeria Police

Applications are invited from suitably qualified persons for enlistment into the Nigeria Police as Women Police Constables.

2. Candidates selected will be required to pass an Entrance Examination into the Southern Police College where they will undergo, as recruits, a six months course of training in Police Duties.

3. On successfully passing out of the Police College they will be appointed Third Class Women Constables and be posted for duty to LAGOS, the EASTERN REGION or the WESTERN REGION.

(a) The following qualifications are required of Applicants seeking enlistment :-

| | |
|---|---|
| Education: | Must be literate and must have reached a Standard of Education equivalent to Class II Middle School Certificate. |
| Age. | Shall not be less than 19 years of age or more than 25 years of age. |
| Height : | Shall not be less than five feet four inches, |
| Character | Must be of good character and must not have been convicted of any criminal offence. |

5. Applicant's must be unmarried, of good physique and devoid of any physical deformities.

6. Application forms may be obtained from the Senior Superintendent in-Charge of the Police Province in which the applicant resides and must be returned to that Officer, Forms may also be obtained direct from the Assistant Suprintendent of Police (Women). The Nigeria Police, Tinubu Square, Lagos.


## CARSON PAINTS AND VARNISHES




SOLE AGENT:-
IKORODU TRADING COMPANY
20 & 28, BALOGUN STREET, LAGOS.




# Omo'ba Gesi mbo wa si Nigeria.

Ọkan ninu awọn ọmọ'ba ilu Gẹsi ti o jẹ ọmọ bibi inu ologbe ọba Gẹsi kan ti a npe ni King Geoge Karun, ẹniti nwọn gbe niyawo fun Ijoye Gẹsi kan ti nwọn npe ni Earl of Harewood ninu ọdun 1922, ni a gbọ wipe o mbọ nilẹ Nigeria, lati wa mọ ibiti a npe bẹ. Ẹgbọn agba l'ojẹ fun ọba obinrin Gẹsi, Elizabeth keji, aburo rẹ lo si jẹ, a bi i ninu ọdun 1897.

Nigbati o ba de sile Nigeria, on ni yio si ile ti nwọn npe ni Teaching Hospital ni ilu Ibadan, ati ibujoko ẹka Nigerian College of Arts ti o wa nilu Zaria.

Ọmọ'ba yi yio lọ si ipade ọgọrun ọdun ti a ti da igbimọ ẹsin ti eti odo Ọya silẹ, ninu ile isin nla alagogo nilu Onitsha. Yio gunlẹ silẹ yi ninu oṣu November, Gomina agba ti ilu Eko lo fi iwe pe e lati wa si awọn ibiti a wi na. Sẹkitẹri agba tilu Oyinbo si fi aṣẹ si.

## Itan awon Oba Yoruba

Alafin Ọyọ gbero lati le Afọnja lọ, o ran a pe ki o lọ ko awọn Ṣabẹ, Afọnja ri pe nṣe ni Alafin fẹ le on ti o fi sọ pe ki on lọ ko awọn Ṣabẹ. Afọnja dahun wipe tani sọ bẹ? Alafin na ma kuku le ran iṣe to le o.

# Alapara Ibadan nki yin o!

OKE FỌKỌ
Ibadan

Arakunrin ati arabinrin mi! Emi ko mọ wipe ko si kekere owo (Trade) siṣe. Bi o nba nlọ si Gbagi lọ gba awin iṣana, owo ni– bi o si tun lọ si Lalupọn ti o ngba koko (cocoa) lori awọn olei komọ kan, owo mọ si ni o.

Otu mo si ni emi Alapara Ibadan ti mo nba yin ṣe awada yi. Nijọ ti mo kọ mọ ilu Ibadan yi, Lalupọn ni mo kọ lọ ba wọn gba aru ekurọ. Wọn ni owo (money) wa lara ọpẹ? Ẹmu l'o ku ti mo mba wọn ru nisisiyi.

Ṣowo lẹṣẹ otu;
Ṣugbọn otu ko ba ẹnikan ja
Jẹjẹ Otu ni Otu nlọ

GBERE RẸ, ẸNAHORO

Awe, emi ko mọ wipe bẹ ni iṣẹ ọlọpa dun to. Iṣẹ ọlọpa mọ dun jọjọ o, karin ki a mọ yan, ka wo enia sunsun ki a gba loju. Ka gba agbe ẹmu lori ẹlẹmu - ki a tun ba iyawo oniyawo sọrọ aṣiri - ka wọ oko - oloko lo ki a gba iṣu.

Awe, Oloye Enahoro mọ ṣe jọjọ o, ti o mu iwakiwa kuro ninu iṣẹ ọlọpa. Awọn ẹlẹmu Ogunpa ti roju raye nisisiyi; ti Akẹsan papa gbadun. Ọrọ a nfun ni ni owo ibọlẹ papa pin - awọn oni mọto a rin falala. Ofin ọlọpa wa ni apo mi, Enahoro ṣe jọjọ.

OFIN ỌLỌPA IBILẸ

Ofin kini:- iwọ ko gbọdọ wọ isọ ẹlẹmu lọ ki o mu ọ'i, ikoko tabi siga. Ofin keji:- ti o fi de ikẹsan iwọ ko gbọdọ wọ mọto ọmọ - ọjẹka ni aisan owo fun, iwọ ko gbọdọ ṣe owo pẹpẹ pa tabi ki o ma je gbese kiri; ranti wipe o ko gbọdọ da si ọrọ ilu ju wipe ki o dibo lọ. Ma ṣe eba owo-ẹhin tabi tiwaju, o ko gbọdọ sun tabi ki o ma sọ ọrọ irana lenu iṣẹ. Ju gbogbo rẹ lọ, igbimọ ilu kan ko le sọ e di ọga mọ - bi iṣẹ rẹ ba yẹ lati bọ siwaju, Ọga ọlọpa ni yio bu ọ lokun si apa rẹ.

Alao, iṣẹ ọlọpa mọ dun o, ka rin ki a tun mọ yan. Ọrọ awada kọ ni eleyi o.

# Ojo Odunni kamama, o si le kenka

EKO. Lati ọdun 1949 si 1950, ni a lero wipe iru ojo gẹgẹbi ti ọdunni ti rọ mọ, Ṣugbọn ti ọdun ni, nipataki kamama, o si tun le kenka; lati iwọn ọjọ mẹdọgbọn sẹhin wa ni ojo yi ti nrọ arọ-aiduro.

Lati ọjọ ti ti o nrọ, a koiti gbọ wipe, o yọ wọn lenu ni Muslim ri ṣugbọn lọdunni, ojo na yọ wọn lẹnu, o si yọ wọn ferigi pẹlu. Nitoripe ojo na rọ wabi-wọsi tobẹ ti agbara ojo wọle lọ ka ẹkọlaya m'ọle.

Ni bareke ọlọpa ti o mbẹ ni Ararọmi, ni ẹhinkule Abari nigbati oju agbara kun tan, omi ya lọ wọle awọn ọlọpa ninu ile wọn, ti tobẹ nwọn ni lati ko jade ni apapandodo. Ojo yi kanna le ya ile kan ni Ọbalende, o wọ'le kan ni Isalẹ-Eko, ọkan ni Idumagbo ati ọkan ni isalẹgangan.

Ojo yi na lo ya dina okun Alasia ni abule Iru, tobẹ ti gbogbo awọn enia ti o nlọ wẹ ninu okun ko ri ọna kọja. Ile ẹkọ Kings College ni ogiri ọgba rẹ ya lulẹ ni apa Igbosere Road. Ni Bareke awọn ọlọpa ti o mbẹ ni Okun Alasia ni omi ti ṣan yika; awọn si ni lati wọ omi ki nwọn to wọ ile wọn.

Agbara ojo ti le gbogbo awọn ara Okun Apẹsẹ jade kuro nile. Ojo na tun ṣe gegele lori gegele, o tun lọ wo ogiri Iga Idunganran. Ha! kili ẹ nfi ọba pe, ọba o, ọba alaṣẹ, ekeji oriṣa.

USED LORRY TYRES
PRINTING PLANT-
CLOTHING
ORGANS-BAND INSTRUMENTS
We export Anything.
ALDERSHOT WAREHOUSES LTD., POUND RD.,
ALDERSHOT, ENGLAND.

# Ministry of Education, Western Region

## Western Region Government Scholarships

The Western Regional Government will be awarding a further 100 scholarships this year to suitably qualified candidates of Western Region origin. The scholarships will be tenable at institutions in Nigeria commencing from the academic year 1957-58 and will generally be tenable at Colleges and Institutions abroad commencing from the academic year 1958-59. Students already studying at institutions abroad however, may, depending upon the recommendations of the Scholarship Board, have their awards made tenable from an earlier date.

2. The Courses for which awards will be made will include:- Agriculture, Forestry, Veterinary, Medicine, Dentistry, Pharmacy, Mental Nursing, Hospital Administration, General degree courses in Arts, Maths & Science, Architecture, Geology, Education, Hides & Skins, Survey and Articles of Clerkship with Firms of Solicitors for training as Solicitors.

3. The awards for survey course will be offered only to members of the Survey Department of the Western Region and separate instructions in regard to these awards will be circularised departmentally.

4. Suitable candidates already serving in the Agriculture, Forest and Veterinary Departments will also be considered for awards provided they hold Grade II Cambridge or West African School Certificates with credit in at least one science subject. All other candidates should ensure that their academic qualification are adequate for direct entry to suitable institutions for degree courses either at the University College, Ibadan or Overseas, as no scholarships will be offered for pre-University training except to those candidates already serving in the Departments named above.

5. Only persons of Western origin will be eligible for awards.

6. Applications for scholarships may be made by candidates of either sex, preference normally being given to those candidates under thirty years of age.

7. The minimum qualification required from any applicant is grade II Cambridge School Certificate with exemption from London Matriculation or Grade II West African School Certificate. Applicants holding only a Grade III Cambridge School Certificate or who have obtained exemption from London Matriculation on the basis of such a certificate will not be considered for an award.

8. In the case of candidates resident in Nigeria, scholarships will not be made tenable abroad where courses are available in this country.

9. Candidates, wishing to proceed to University College Ibadan or to the Nigerian College of Arts, Science and Technology, to undertake courses of study which are available there must apply direct to the College Authorities to sit for examinations in accordance with the procedure prescribed and will not be eligible for awards unless they have been accepted for entry by the College Authorities.

10. Candidates applying for courses of study at institutions outside Nigeria should ensure that their academic qualifications are sufficient to enable them to be placed in suitable institutions to undertake degree courses as soon as selected, as scholarships abroad will not be offered for General Certificate of Education (Advance level) Courses or equivalent examinations.

11. Applications from persons holding degrees wishing to be trained as Solicitors will also be considered. The period of training for persons holding a degree is three years and five years for those without degrees.

12. All applications for scholarships must be completed in duplicate on the prescribed forms which may be obtained from:- All provincial Education Offices in the Western Region. The Secretary to the Scholarship Board, Ministry of Education, (Students Division), Ibadan ;

The Official Secretary, Office of the Commissioner for the Western Region, 26 Grosvenor Gardens, London, S.W.1;

The Nigeria Liaison Officer, 506 Dupont Circle Building, Washington 6, D.C. ;

13. Application forms must be completed in duplicate and returned direct to the Secretary to the Scholarship Board, Ministry of Education, (Student Division), Western Region, Ibadan, through Heads of Department in the case of Government employees, and through Principals of Schools or Colleges or through employers as appropriate in all other cases and should be received not later than 15th September, 1957.

14 Central or Regional Ministers must not be given as referees, and applicants who resort to canvassing will be disqualified.

15. Successful candidates will be required to enter into bonds to serve the Western Regional Government for period of not more than five years after the successful completion of their courses of study.

MINISTRY OF EDUCATION,
Western Region,
Ibadan, 26th July, 1957.

## Oba l'ola



Aworan ọmọ'ba Charles tiin Gesi'di a mọ ayẹgbi ọba l'ola ni a a ewe ti o gun igi ti aburo rẹ obinrin nṣire nisalẹ idi igi na yi, nina agbala Igbadun ọgba ile ọba.


## Imoran Fun Enyin Abiyamo

Enyin abiyamọ ẹ wa ra ỌMỌRELA o dara pupọ fun awọn ọmọde.

Ama jẹ ki ọmọde ri orun sun daradara o dara fun otutu, ikọ ati orisirisi arun miran ti o ma mba ọmọde ja ni asiko chin. Ọpọlọpọ abiyamọ lo ti lo egbogi yi fun ọmọ wọn ti wọn si sọ wipe o dara pupọ fun awọn ọmọde

ỌMỌRẸLA BABY MIXTURE

(Ṣile Meji Abọ 2/6d Fun Igo Kan)

O wa Lọdọ

COMMERCIAL MEDICINE STORES

(Qualified Chemist)

10, VICTORIA STREET, LAGOS.

## Office Of The Commissioner For The Western Region In The United Kingdom - Vacant Post

Applications are invited from suitably qualified Nigerians of Western Region Origin for appointment to fill the following posts in the Public Service of the Western Region, Nigeria.

Successful candidates will be posted to serve in the London Office of the Commissioner for the Western Region in the first instance but will be liable to transfer at any time to comparable posts in Nigeria.

| Item No. | Designation | Duty Post | Gorsuch Salary (at rate) |
|---|---|---|---|
| 1. | Administrative Officer | Assistant Students' Officer. | £624x36-696; 804x42-1,140; 1,180x48-1,380 |
| 2. | Assistant Trade Officer | Assistant Trade Officer | £600x30-780 816x36-972 1014x42-1140. |

Note:

An overseas duty allowance of 30/- for the first twenty-eight nights in the United Kingdom and 24/- thereafter is payable to officers normally domiciled in Nigeria.

For full particulars and method of application see Western Region of Nigeria Gazette No. 32 Vol. 6 Notice No. 634 of 11/7/57

Closing date:

For candidates in the U.K. 10/8/57.
All other candidates 20/8/57.

## Notification of Addresses

The Director of Education, Western Region, wishes the following persons to inform him of their present address :-

| Name | Last Known Address |
|---|---|
| 1. Musa A. Ọlakisan | Baptist School Igbogila via Ilaro |
| 2. Adetola A. Odukogbe | Local Government School, Arijan, Ijebu Waterside |
| 3. Miss Angela Nwaturuocha | R.C.M. School Topo, Badagry. |
| 4. Michael A. Ogunkunle (Ogundairo ?) | Methodist School, Ode, Aye, Okitipupa |
| 5. Francis O. Ajayi | Colony T.T.C., Igbogbo, Ikorodu. |
| 6. Michael L. Ogunnaiya | Holy Trinity School, Aiyepe, Ijebu Province. |

The Director is anxious to communicate with the above persons in connection with matters pending before the Teachers' Council constituted under the Western Region Education Law, 1954, and which will have to proceed in their absence if they cannot be found.

DIRECTOR OF EDUCATION, Western Region.

## Idahun Si Ibere

Olotu,

Jọwọ gba mi laye lati fesi si ẹrẹ ọrọ Ọgbẹni Ọlaturoji ti o ngbe (14 Aibu Street) ti o jade ninu Iwe Irohin ti ọjọ Saturday, July 27th 1957 ni oju ewe kẹji ti o sọ wipe emi sọ pe Owu ati Oke-Onigbin nja; ṣugbọn bẹkọ ni ọrọ na ri o.

Ohun ti a wi niyi — "to yẹ ki ọmọ Owu ẹba Oke Onigbin ba ara wọn ṣe ọrẹ pọ". Ibiti nwọn ti tẹwe na ni wọn ti ṣi ọrọ yi tẹ. Apejuwe rẹ ni eyi; ẹnyin na, ẹ wo iwe yin ti ẹ kọ sinu Iwe Irohin yi, ẹnyin na yio ri wipe, ẹ ri iwe wa ti ẹ sọ wipe a kọ si ita ni July 6th, 1956 ni ṣugbọn July 6th, 1957 ni a kọ iwe si ita bẹni ki iṣe wipe Oke-Onigbin ati Owu nja rara, awọn ti nwọn tẹ iwe ni nwọn ṣi tẹ o.

Ọgbẹni Yusufu Ọlaturoji, nigbati iwọ na sọ ninu iwe ti o kọ sita wipe o da ẹ ni oju gbangba wipe awọn Kiriyo Owu ati Imale Owu ko ja rara. Kini o ṣe ti Ọlọpa fi wa ni July 19th 1957 ti o si pe gbogbo awọn Ijoye ati Kiriyo ati Imale Owu jọ ti o si bi wọn ni ẹjọ ni July 20th, 1957 ni ile alagba kan, ti nwọn si mu enia mẹjọ lọ si Ilọrin.

(Kolti pari)




## Baba be oku ọmọ rẹ, o gbe ju s'odo ọsa.

Ọkunrin ara Ilajẹ kan ti o to ọmọ ọgbọn ọdun lọjọ ori rẹ, ni awọn ọlọpa ọba ramu fun ẹsun wipe, ọkunrin na gbe oku ọmọ rẹ ju sinu odo ọsa.

Iṣẹ ọdẹ ap'ẹja ni ọkunrin na nṣe, orukọ rẹ a ma jẹ Tijani Ladipọ, on ni ẹniti o ju ọmọ rẹ obinrin ọmọ ọdun kan ti orukọ rẹ njẹ Biatu sinu odo ọsa, l'abule Ọkọya l'oke Ebute-metta, ni ọjọ Monday ọsẹ tokọja.

Nigbati nwọn mu ọkunrin yi de iwaju adajọ, o sọ wipe mo bẹrẹ f'oji o, ọrọ edun gidigidi ni temi yi, o di ekefa ti emi pelu iya ọmọ na ti mbi ọmọ na ti o nku ti mo si nsinku re, mo wa ro'pe sisin ti mo ma nsinku re l'ọsẹ fun nku, ni mo ba ṣe pinnu wipe nko ni sin oku rẹ lọtẹyi, ngo lọ ju si odo ọsa ni, lati le gba kuro lọwọ awọn ẹmi eṣu ti o mba rin l'orun.

Ṣiwaju, ni awọn ọlọpa ti sọ fun adajọ wipe nigbati awọn gbọ iro wipe ọkunrin yi gbe oku ọmọ rẹ ju s'odo ọsa ti awọn si lọ mu o sọ fun wọn wipe gbogbo owo iṣe on ni ọmọ na ma nwa danu ki o to ku. On kosi ni owo lati fi gba iwe isinku rẹ lọdọ Ijọba.

Adajọ sọ wipe Kotu yio fi oju anu wo ọ, on yio si fi eyi ṣe ikilọ fun ọ wipe ki o ma dan iru iwa bẹ wo mọ - ki o lọ san poun kan (£1) sapo Ijọba. Nṣe ni Tijani dọbalẹ gbalaja, ti o wipe mo dupẹ fun ọ, baba mi, nko jẹ tun dan iru rẹ wo mọ.




Printed and Published by The Union Printing and Publishing Company. 28, Kosoko Street P. Box 467 Lagos Phone 23?